# JAGUNJAGUN FUN JESU

### Efesu 6:10-24

### ẸKỌ 404 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: 'Ẹ gbe gbogbo ihamọra Ọlọrun wọ̀, ki ẹnyin ki o le kọ oju ija si arekereke Eṣu" (Efesu 6:11).**

**Imurasilẹ fun Ogun**

Njẹ o le fi oju inu wo agọ awọn jagunjagun kan – boya eyi ti iwọ paapaa ti bẹwo ri nigba ti baba tabi ẹgbọn rẹ ọkunrin wà ninu iṣẹ ologun? Ohun kin-in-ni ti iwọ ri nigba ti o de enu ọna ni awọn ile ti o lọ lọwọọwọ ninu eyi ti awọn ọmọ ogun n gbe ti wọn si n ṣiṣẹ. Siwaju si i o ri awọn eniyan ti o duro nihin tabi lọhun lori papa. Awọn miiran n to lọ lọwọọwọ. Awọn miiran n kọ́ bi a ti n yin ibọn. Awọn miiran n kọ bi a ti n wa ọkọ ofurufu. Gbogbo awọn wọnyii ni o n kọ bi a ti n di jagunjagun, ti wọn si n kọ bi a ti n ja ogun. Bi o ti wọ inu ile kan lọ, boya o le ri oniṣẹ-ọwọ kan ti o n ṣiṣẹ lara ẹya ọkọ̀ ofurufu. Ninu agbala tabi ile ijẹun o ri awọn alase ati awọn agbáwo. Nibomiran o ri awọn ti n pin aṣọ awọn ọmọ-ogun fun awọn ti wọn o si ṣe akọsilẹ ohun ti wọn pin fun awọn eniyan. Gbogbo nnkan wọnyii ni wọn n ṣe fun aabo ilu wa.

**Ogun ti Ẹmi**

Igbesi-aye Onigbagbọ́ jẹ ti ogun jija pẹlu. Gẹrẹ ti ọdọmọdekunrin tabi ọdọmọdebinrin kan ba ti ri igbala, eṣu yoo wá lati fẹ gba igbala rẹ̀ sọnu. A ni lati ni ifẹ lati ba Satani jà ki a ba le pa igbalà wa mọ́, gẹgẹ bi a ti n kọjuja si awọn wọnni ti o n gbiyanju lati gba ilu wa lọwọ wa. Bi a ba jẹ oloootọ Onigbagbọ, Ọlọrun yoo wà ni iha wa. O n fẹ ki a jẹ alagbara ọmọ-ogun ti yoo gbogun ti eṣu ti ki yoo si fi ẹyin silẹ. Ọlọrun ti pese ihamọra pipe fun aabo ọkàn wa, O si paṣẹ fun wa ki a gbe e wọ̀ -- gbe gbogbo ihamọra Ọlorun wọ̀ ki awa ki o le kọ oju ija si arekereke tabi ọgbọn ẹ̀wẹ èṣu.

**Aabo Wa**

Gbogbo ọmọ-ogun ti o wà ninu iṣẹ ologun ni orilẹ-ede wa ni lati jẹ alagbara. Olukuluku wọn ni a n ṣe idanwo fun ki a to gba a. Ninu ẹ̀kọ ti oni, Bibeli paṣẹ fun olukuluku ti o ba wà ninu ogun Ọlọrun ki o jẹ alagbara ninu Oluwa, ati ninu agbara ipa Rẹ. Bi o tilẹ jẹ pe awọn ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin kò lagbara nipa ti ara sibẹ wọn le fi taratara gbe ọkàn le Jesu ki wọn si di alagbara ninu Rẹ̀.

Ohun kin-in-ni ti a n kọ́ ọmọ ogun ni ijolootọ si ilu rẹ ati igbọran si aṣẹ awọn ti o ga ju u lọ ninu iṣẹ. Awa, gẹgẹ bi Onigbagbọ, ṣe ileri lati jẹ oloootọ si Kristi. A sọ fun Ọlọrun pe a o jẹ olooотọ si I; a o ba A rin ni gbogbo ọ̀na naa lọ si Ọrun; a si ṣeleri lati gbọran si aṣẹ Rẹ̀. Ọta wa ẹmi a maa gbiyanju lati mu wa ṣe alaiṣootọ si ilu wa Ọrun, eyi ti Jesu i ṣe Ori rẹ̀. Eṣu a maa gbidanwo lati mu wa ṣaigbọran si aṣẹ ti Jesu Balogun wa pa fun wa. Jesu ni Balogun wa, awọn aṣẹ Rẹ̀ ni a si kọ silẹ ninu Bibeli.

A kò le fi oju wa ri eṣu ọta wa, ṣugbọn oun wà. A ko fi oju wa ri Jesu ṣugbọn Oun n gbé inu ọkàn wa, a si mọ pe Oun wà nitori wa. Ọta wa ẹmi lagbara, ṣugbọn Jesu lagbara ju u lọ. A kò bẹ̀ru eṣu, ṣugbọn a n bọla, a si n ni ibẹru ẹni iwa-bi-Ọlọrun fun Jesu, Balogun igbala wa.

**Ihamọra**

Olukuluku ọmọ ogun ni a n fun ni bata ti o lagbara lati fi rin. A fun un ni aṣibori lati daabo bo ori rẹ̀. A fun un ni ibọn, a si kọ ọ lati loo. Nigba ti o ba wà ni ilẹ ọ̀ta o gbọdọ ṣọra gidigidi ki o má bọ sọwọ ọ̀ta ki a si mu un lẹru.

A kà bayii pe ihamọra kin-in-ni ti Ọlọrun ti pese silẹ fun awọn ọmọ-ogun Rẹ̀ ni otitọ. Njẹ o mọ ohun ti otitọ jẹ gan an? Idahun si ibeere yii wà ninu Bibeli nibi ti a ti le ri idahun si gbogbo ibeere wa. Jesu wi fun ọ̀kan ninu awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe, "Emi li ọ̀na, otitọ, ati iye" Nigba ti a ba sọ otitọ ki i ṣe pẹlu ẹnu wa nikan, ṣugbọn ninu ọkàn wa, bi o ti lẹ jẹ́ pé o lè mú inunibini wá tabi iyà, ó maa n sọ wa di alagbara. A maa n di alagbara ninu Ọlọrun nitori Jesu ti i ṣe otitọ ti ràn wá lọwọ lati sọ otitọ.

Otitọ dabi amure yi ọkàn ati àya wa ká. O n fun wa ni agbara lati mu gbogbo ero wá si igbekun ni igbọran si Kristi. Nigba ti idanwo ba de, a o gba aṣẹ Kristi gbọ́ a o si kọjuja si eṣu.

Ihamọra miiran ti a tun fun wa ni igbàya ododo. Jesu ni ododo wa, ati ṣiṣe ohun ti o tọ́ -- ohun ti o dabi ti Kristi – dabi irin lile pẹlẹbẹ ti o dabobo ọkàn wa, ibi ti o ṣe pataki ju lọ ninu ara wa. Nibomiran ninu Bibeli, a sọ nipa abo yii gẹgẹ bi igbaya igbagbọ ati ifẹ (1 Tẹsalonika 5:8). Bi a ti n sọ igbagbọ wa di lile ninu Jesu, ti a si n sọ ifẹ wa di gbigbona ninu Rẹ, a ki yoo ṣẹgun wa.

Fun ẹsẹ wa ni imurasilẹ Ihinrere alaafia wà. Ẹsẹ wa wà lati ṣiṣẹ igbọran. Ọkan ninu aṣẹ Balogun wa ni, "Ẹ lọ si gbogbo aiye, ki ẹ si ma wasu ihinrere fun gbogbo ẹda" (Marku 16:15). A le sọ fun awọn alabaṣire wa nipa Jesu, boya olukọ wa pẹlu; a le sọ fun awọn iya ati baba wa bi wọn ko ba ti ri igbala. Ọlọrun yoo ṣi àye silẹ fun wa bi awa ba ni ipinnu lati ṣe ohun ti Oun palaṣẹ. Lai pẹ ọjọ, awa yoo ni ipin ninu ijọba alaafia ti Jesu yoo gbe kalẹ ninu ayé.

A ni lati mu apata igbagbọ nipa eyi ti a o fi le pa ọfa iná eṣu. Ọfa ti eṣu n ta kun fun ina. O fẹ ki wọn lẹ mọ àya wa timọtimọ ki o ba le kun fun ibinu, ègan ati ero buburu ti yoo pa ọkàn wa run. Ṣugbọn ninu ileri Ọlọrun, a o gbe apata igbagbọ soke, iná naa yoo si kú. Ọfa ti eṣu lero pe yoo pa wa run yoo bọ silẹ lai si ipalara labẹ ẹsẹ wa. Nitori Ọlọrun ti ṣe ileri pe Oun "ki yio jẹ ki a dan nyin wò jù bi ẹnyin ti le gbà; ṣugbọn ti yio si ṣe ọna atiyọ pẹlu ninu idanwò na" (1 Kọrinti 10:13).

Gbogbo awọn ti o ba gbọ́ Ọrọ Ọlọrun pẹlu ọkàn ti o ṣipaya, ti wọn si n kà ti wọn n kọ́ ẹkọ Bibeli nibi ti awọn ileri Ọlọrun wà, awọn ni ọmọ ogun ti o dara ju lọ. Awọn ni o le fi irọrun gbe apata igbagbọ soke nitori "nipa gbigbọ ni igbagbọ́ ti iwá, ati gbigbọ nipa ọ̀rọ Ọlọrun" (Romu 10:17).

Aṣibori igbala ni o kàn. Ireti wa ni pe Oluwa Jesu yoo pa wa mọ́ ni abẹ Ẹjẹ Rẹ̀ iyebiye, yoo si ran wa lọwọ lati bori gbogbo ogun ti èṣu n ba wa jà lojoojumọ ati ni gbogbo igba titi Jesu yoo fi pada wá.

Ida Ẹmi ti i ṣe Ọ̀rọ Ọlọrun ni a darukọ kẹyin nitori pe on ni ihamọra ti o lagbara ju lọ. Bibeli wi bayii pe, Ọ̀rọ Ọlọrun yè, o si li agbara, o si mú jù idak'ida oloju meji lọ" (Heberu 4:12). Jesu lo o nigba ti oludanwo ni wá si ọdọ Rẹ̀. Ni akoko kọọkan Jesu wi bayii pe, "A ti kọwe rẹ̀" ati nikẹyin èṣu fi I silẹ lọ.

**Ṣora ki O si maa Gbadura**

Nikẹyin gbogbo ihamọra ẹmi wọnyii, a sọ fun wa pe ki a gbadura. A sọ fun wa nigba ti a ni lati gbadura, bi a ṣe ni lati gbadura ati ẹni ti a ni lati gbadura fun. A ni lati gbadura nigba gbogbo. A gbọdọ gbadura pẹlu gbogbo adura ati ẹ̀bẹ ninu Ẹmi. A ni lati ṣọra ninu adura gbigba ki eṣu ki o má ba di wa lọwọ tabi ki o mu wa ṣiwọ adura wa ki a to ri idahun si adura wa gba. A ni lati gbadura fun gbogbo awọn eniyan mimọ́. A ni lati gbadura fun ara wa ati fun ẹni kọọkan ninu awọn ẹgbẹ wa ti o wà ninu Ihinrere; ati ni pataki fun awọn alufaa wa, awọn alakoso wa, pe ki wọn ki o ba le waasu Ọrọ Ọlọrun pẹlu igboya gbogbo gẹgẹ bi Ọlọrun ti n fẹ ki wọn waasu.

**AWỌN IBEERE**

1 Ninu ipá ta ni a gbọdọ di alagbara gẹgẹ bi ọmọ-ogun Onigbagbọ?

2 Ki ni ṣe ti o ṣe jẹ danindanin fun wa lati gbé gbogbo ihamọra Ọlọrun wọ̀?

3 Ta ni awọn ijoye ati ọlọla ti a n bá jagun?

4 Darukọ awọn ohun ija mẹfa ti a mẹnu kan ninu ẹ̀kọ wa ti oni?

5 Nigba wo ati bawo ni a ṣe ni lati gbadura? Fun awọn wo?

6 Ki ni ṣe ti Paulu fi n fẹ ki awọn Onigbagbọ́ Efesu gbadura fun oun?